GO PLACES IN A HILLMAN FROM ARAB BROS MOTORS LTD.


# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLẸ DE, OKUNKUN PARADA.


**AKIYESI**

A fi eyi se ikede pataki fun gbogbo eyin Omo ... Imole Aiye wipe, gbogbo iwe ti e fi ranse si a ti gba, awon elomiran lero wipe boya, ako ti iwe won ti akoko gba ti ko jeki a pari, Sugbon a nse eto nipa re lowo, Nigbati iwe na ba jade, olukuluku yio ri oru ko ti ara re nibe.

AKOWE AGBA EGBE IMOLẸ AIYE

VOL. V No. 203 MONDAY JULY 17 — JULY 23 1951 KỌBỌ KAN (1d)

## Gbomo fun Olomo, Alagbato ko mo iyi Omo.

# Bintu wo Ewon odun meji-abo nitori o ji Omo gbe

ABẸOKUTA:- IROHIN KAN WA LATI ILU ABẸOKUTA WIPE, OBINRIN GBAJUGBAJA KAN TI ORUKỌ RẸ NJẸ BINTU ASHABI, NI ADAJỌ KOTU LA MỌ ẸWỌN ỌDUN MEJI PẸLU ABỌ, NITORIPE OMO WU U LATI BI, ŞUGBỌN KO RI ỌMỌ BI O WA LỌ JI ỌMỌ TI ẸLOMIRAN.

Bi a ti gbọ pe, ọrọ na'lọ biyi, Bintu Ashabi yi ti fi akoko kan ṣe Iyawo Ọgbẹni kan ti wọn npe ni, Rafiyu Ishọla nigbati o wa ni Abẹokuta, şugbọn ni gbogbo akoko ti nwọn fi ngbe papọ, nwọn ko bimọ fun ara wọn, akoko na jẹ ọdun 1957. Lẹhin na ni isẹ wa gbe Rafiyu lọ si ilu Sokoto. Ni ọdun 1961 nigbati Ọgbẹni Ishọla pada wa si Abẹokuta, ti on pẹlu Bintu Ashabi tun ri ara wọn, Bintu sọ fun ọkọ rẹ atijọ wipe, on ti fẹraku ki o to lọ si ilu Sokoto, on si ti bi ọmọ na nisisiyi, ki on to le gbe ọmọ na fun, on yio gba Pọun mẹwa ṣandi lọwọ rẹ.

Ori Rafiyu gbona, o wipe, hẹ! laiye on, on ri ẹniti o bi ọmọ fun on, ni wara-nṣesa, o ka Pọun mẹwa fun Bintu, o ni ki o lọ gbe ọmọ na wa. Nigbati o gba owo na tan, lọ ba kori si arin oja Itoku. Nigbati o ri ọmọde kekere kan, lo ba joko ti, o ra akara fun, o ra inoyinmoyin fun, awọn ọlọmọ nsọ wo, bi o ti dide, lo ba gbe ọmọ ọlọmọ pọn ṣẹhin, wọn jẹ ki o rin bi ẹsẹ mẹwa, ni wọn ba ke ibosi ole le lori, ki Ọlọpa to ki mọlẹ

Maṣe fi owuro ṣere, nitoripe, igbẹhin lo ndun oloku ẹda, ngo ṣe isẹ agba, lo nmu ọmọde gba ele, ngo ṣe isẹ ogo, oko olowo lo nmu ọmọ lọ

## ATOKA


| | |
|---|---|
| OWUYE, SANNI ERIN, ỌRỌ OLOTU, NIMỌTA ILARO | EWE KEJI |
| ỌRỌ PATAKI FUN AWỌN OBINRIN | " KẸTA |
| PETEPETE ODO TI GBE OMUWẸ | " KẸRIN |
| ALAYE NIPA OMUPO IPOLOWO ỌJA | " KARUN |
| IROHIN ALADUN | " KẸFA |


## Oba Adele nrin, o nyan rigboro Ilu Oyinbo.



Kabiyesi Alaiye Iuwa Oba Musandiku Adele, ti ilu Eko ni a nwo ninu aworan yi nigbati on pelu iyawo re ati Oloye Eletu Iwaṣẹ. Ni ilu Liverpool ni nwọn koko gun'lẹ si, ibẹ na ni nwọn wa ti a nwo wọn yi ... lo wo ilu kekere kan ti a npe ni Portsunlight nibiti ọṣẹ ... o atakuyẹ ... kan ti nwọn npe ni Lever Bros gbe kọ ile isẹ ... kan si. Ọba Adele mura gẹgẹ bi ọba, o ko lẹkẹ si ọrun, iyawo re Olori si ntẹle pẹlu Ọgbẹni A.B. Gbajumọ ti ise Oloye Eletu Iwaṣẹ On pẹlu Ọlọla Gomina Agba ... ara wọn ninu Oyinbo lẹhun nwọn gbọwọ nwọn si ki ara wọn.

Adura wa ni wipe ki Ọlọrun mu ẹsẹ awọn ijoye wa nwọnyi pada wa ba wa pẹlu alafia ati ara lile.

# Imoran fun awon omo Ibile Igbomina

Lati Owo:- SANNI ERIN

Olotu jowo gba mi laye ki emi Sanni Erin ba awon omo ilę Igbomina to fara mo ęgbę Afęnifere soro, emi Sanni Erin fę tu pęrpęn iwa awon ęgbę N. P. C. ti nwon nhu laito ni ilę Igbomina, akoko ninu iwa won na ni pe, gbogbo omo ęgbę ti o ba ti lo di si ti won Nwon feran lati mu fi iya ję nwon, ki won si ma ka ęsę u won kose si won lorun lati ba le fi iya ję won, Ni atijo ti alaiye ti daiye ni pe ęnikeni ninu ilu lo le se ęgbę ti o ba wu. Ijoba kan ko le pa enikeni la se lati șe ęgbę ti o ba ję pe ko fę șe, ki nwon wo awon Ipinlę mejeji ti o ku (East & West) e wo lo ofi iya ję omo ęgbę N. P. C. nitori pe ko șe ęgbę A. G. tabi e wo lo nfi iya ję N. P. C. na n teripe ko se N. C. N. C? iru iwa o d a l ę bayi lo ję nkan ti o le da Ijoba Ipinlę ru patapata, ki nwon si ma roju ati șe Ijoba nwon ndori nko ori awon e n i a ti won fi iya ję le ju ti won lo ati papa pe, Olorun loke ori gbogbo iwa odalę ti nwon se bi Oba si ma dajo fun won ada tan ni. Emi Sanni Erin fę so idi pataki pe awa omo Igbomina (Yoruba) ko lę lo ati ma ba N. P. C awon omo (Hausa) da nkankan po, a koko ni pe, a ki ișe Hausa, ęlękeji o yę ki a le ja fun ilę Igbomina lati da duro gede gbe, ka dę mo pe ija ti ęgbę Afęnifere nba wa ja ni pe, omo iya nwon ni awa ase, tabi n i n u awa omo Igbomina wo lo fę șe Ęru Hausa titi lai? A si fę bo ajaga iya ti awon Hausa alaimęto fi nję wa ni ilę Igbomina kuro, ę wa nkorira. Mo bę gbogbo ęnyin ojulowo omo ilę Igbomina ka lo di si Ijoba Hausa N. P. C. awon oni fun osi lati oke de ilę.

Mo ti lę wa bi awon odalę omo ilę Igbomina ti o nșe ęgbę N. P. C. pe, nkan wo ni won șe fun wa? nwon ko fun wa nina, nwon ko fun wa iomi, a nda owo ori nwon ko tun fun wa loda, a si mo pe ęniti o ba ti nda owo ori, eto ni ko je anfani owo ori ni ilu. Iwo omo ęgbę N. P. C. anfani melo ni won fun ę, awon Baba wa to ti nsin won șe bi iya ni won fi san esan fun won, ki awon ęgbę Olomi wa lo ro ori ki won wa mo wipe ęsin ko gbo gun? Ti o ba ri nkan ti awon ęgbę Olomi ti se ni ilę Igbomina, mo fę ki ę wa so.

WO IYOKU NI OJU EWE KĘFA

# Alhaja Nimota Ilaro Soyigi titun

YABA:- Irohin ko to afojuba ni ita Yaba nigbati gbajumo Alhaja Nimota Ilaro Soyigi fun, Ogbeni Onisowo kan ti o nje Adio Mogaji Jura, a gbo wipe omo ilu Epę ni Oko Iyawo yi, ati wipe, on na pelu ję Olowo ati gbajumo, Olowo meji lo fę ara won, gbajumo meji lo si mba ara won sere po.



A gbo wipe Alhaj a Nimota Ilero ni yio șikęta awon Iyawo ti Jura yio gbe ni Iyawo. Alhaji Șodęhinde ni a gbo wipe, Oke wutuba nibi Nikayi na. Awon enia nlanla męta ti o wa nibi isoyigi na ni Alhaji Salawu Ilaro, Alhaji Lemomu Mosalasi Oladimeji, ati Alhaji nlanla kan ni mosalasi Forobe. N i n u aworan wa oke yi, Alhaja Nimota Ilaro, ęniti o ti lo si Meka nigbameji ni a nwo i i owo otun, Oko rę ni a nwo lowo osi ti mu Iyawo rę dani girigiri lati fi han bi won ti fęran ara won to.

# ORO OLOTU

## ILE NI ATI NKĘȘO RODE

O DARA pupo lati ni ęgbę nla kan ti yio sowopo lati șișę fun alafia gbogbo ilę enia dudu. Eyi yio ti lę ję ki ilu miran ni agbaiye mo pe ilę enia dudu ko kere lawujo, nwon ko si ni le fi iwon lo wa

Ko si ęniti, ko mo nipa iya ti awon alawo funfun fi nję awon enia wa ni ilu okere bi Kenya, Algeria, ati Angola. Șugbon nigbati a ba nsoro iya ti oyinbo fi nję enia dudu a ma ngbabe iya ti awon enia wa fi nję awa na nihin. Awa ko si lati toka Ijoba ipinlę kan tabi ęgbę oșelu kan ninu oro yi, șugbon o yę ki okan irufę ijoba tabi ęgbę Oșelu bę ma ,ę won leri. Ile ni a ti nko ęșo re ode, bi a ko ba fę ki Oyinbo ma se wa bi ęru, ki awon Olori tabi Ęgbę Oșelu ye șe awon ti ko fę ti won bi ęran.

Atata oro ni pe o yę ki irępo wa larin gbogbo ilę enia dudu. Laisianiani anfani eyi yio po pupo, nigbana gan ni a o wa di așoro șę bi idi igi nla, șugbon irępo melo ni o wa ni arin wa nihin? Pupo ninu ero ęgbę Oșelu kan ni o wa lati pa ęgbę Oșelu keji rę pata pata. Bawo ni eyi yio șe mu Irępo wa si arin wa? Ile ni a ti nko ęșo re ode, nigbati abę ile ko suuwon, bawo ni iti yio ha șe șe dara? Ę ję ki akoko șe ęșo wa ri'e, ki a le ri ohun ko lo sode.

Nigbati ko ba si irępo ni ile bawo ni ao șe le șișę tokantokan fun irępo ilę Afrika?

# OWUYẸ

## AȘORO SO BI ORO, ORO LOPA ĘNIKAN LI ANA.

Lati Owo:- **Omo Oke Ibadan**

Ękaro o! gbogbo ęnyin omo yoruba, gbogbo nyin ni mo ki, nko ni olodi kan, mo ki nyin lati Eko titi lo de ilu Pota, mo si tun ki nyin lati ilu Eko titi lo si Oke-Oya ati lati Eko titi lode Onitsha, mo ki nyin tęso tęso, tologun-togun Mo ki awon orę mi Ibini Arokuntayo wipe Koyo! awon ara Onitsha Nna ati awon ara Oke Oya wipe Sannu-Inakuana. Ki ę tęti silę, ki ę gbo labari oro mi owuro yi, Owuyę de! așoro so bi oro.

IJOBA IBILE MUSHIN.

Ni owuro kutu-kutu yi bi ęro asoro ma gbesi tibęrę si wipe Ninu ikoko dudu li ati nse obę ni mo ti dide lati lo bę ile ișę Ijoba ibilę Mushin ti o mbę ni oporo Isolo Road. Modakę, mo nwoye, o pę dię ni mo ri awon oșișę ibę, ti nwon bęrę si de, lati wa bęrę ișę onję ojo won, beni mo bęrę si fi ede ęna ki won lati inu afęfę wipe Good Morning Laipe na ni akowe agba ti ijoba ibilę wo moto Ayokęlę de, ki o to bo sile mo ti ra sinu apa rę, emi pęlu rę si jijo wo ile ișęrę lo. Mo kesi wipe, afara kosi ișę oda nitori, ejęki ,lo lę awon ona moto ti owa ni agbegbe Mușhin wo. Jęki agba ita Șokunbi, ati Șadare ati Odusami ki a si Pada wa jasi ita Kandoso, Nigbati a de ita Kandoso ęrin a pa enia nigbati moto kole lomo, ti o ję wipe nșe ni a ni lati bosilę ninu moto,ti a si ka șokoto wa soke, gbogbo ara moto ko șe ri mo fun pętępętę

N'tori irin ajo ti emi pelu rę rin yi, a ni ireti wipe idibo ijoba ibilę ti ipinlę Iwo Orun, ti o mbo yio tun ni ayipada siti Adegbenro. Ęku ipalęmo o.

# ORO PATAKI FUN AWON OBINRIN

Lati Owo:- IYAFIN ALAKE (Eko)

Mo ki gbogbo ẹnyin ẹlẹgbẹ mi lobinrin, mo si tun ki gbogbo ẹnyin Ọnkawe Irohin Imọlẹ kakiri Agbaiye, mo si tun ki Olotu iwe Irohin Imọlẹ na, ẹ ku iṣẹ o. Ọkọ Ọba ko ni ṣa yin lẹsẹ o, Ajinde ara yio ma jẹ fun gbogbo wa o, a ko ni ri ohun gbe sọnu bi kọṣe ibi ọmọ. Agan atọwọ bosun, ẹniti o bi ko ni yan ku o. Amin.

Emi Alakẹ ti ṣe tan lati ma ba awọn Obinrin ẹlẹgbẹ mi sọrọ, nitori o ti to ọjọ mẹta ti mo ti fẹ kọwe si olotu lati ma gba mi laye, lati le ma fun awọn Obinrin ẹlẹgbẹ mi ni imọran ati ọrọ iṣiti ni ọsẹsẹ, ṣugbọn emi ko ri aye nigbana. Ṣugbọn nisisiyi mo ti ri aye, mo si ti mura lati ma fun yin ni ọrọ iṣiti ati imọran, ki si ṣe Obinrin ni kan ati Ọkunrin na pẹlu, emi yio si si tun ma fun yin ni imọran ti o ba kọwe bere nipa Ifẹ, ki nto berẹ ọrọ mi ti ọsẹ yi mo ni lati sọ fun Ọkunrin tabi Obinrin lati bere ibere ki bere ti o ba fẹ lori Ifẹ.

Ọrọ mi ti ọsẹ yi ko pọ, ṣugbọn lagbara Ọlọrun ni ọsẹ to mbọ ẹnyin yio gbadun mi, nitori mo ti mura silẹ dada. Ọrọ mi, ẹ ma ni itẹlọrun fun Ọkọ yin, ohun ti Ọkọ yin ba ṣe fun yin, ẹ jẹ ko ma to yin, ki ẹ si ma gbọrọ si Ọkọ yin lẹnu, ẹ ye ma jaju mọ Ọkọ yin mọ, ki ẹ si ma ni iteriba fun ọkọ yin, o pọ ninu awọn Obinrin isisiyi ti nwọn ma ṣe bi o ti wun wọn nile ọkọ nigbati o jọ pe ọkọ ni o nsan owo ile ti iwọ iyawo si nṣe bi o ti wun, ọkọ yio lo si ibiṣe lati ewarọ eyiti ọkọ ba fi tete tọju onjẹ silẹ fun ọkọ rẹ oti fi ṣe iranu kiri ni iwa bayi kodara, ẹ jẹki a ma tọju awọn ọkọ wa dada ki a ma mọ ohun ti o tọ yatọ si eyiti kotọ, ki a si ma ni suru fun ọkọ wa, mo bẹ yin ẹ ye ma gboju mọ awọn iya ọkọ wa, iru iwa bayi kodara o gẹgẹ bi mo ti sọ wipe ọrọ mi ti ọsẹ yi ko nipọ mo duro bayi. Ṣugbọn lagbara Edunmare ẹnyin yio tun ma gbadun mi siwaju si ni ọsẹ to mbọ.

ANFANI FUN ẸNYIN ỌKUNRIN ATI OBINRIN

Mo fi eyiyi kede fun gbogbo ẹnyin Ọnkawe Irohin Imọlẹ lobinrin ati lọkunrin pe aye wa lati bere ibere ki bere ti ẹ ba fẹ lọwọ emi Alakẹ nipa ọrọ ọkọ pẹlu Aya tabi lori Ifẹ. Ki o ranṣẹ si:-

IYAFIN ALAKE
c/o OLOTU IROHIN IMOLE
16, Bamgbose Street,
LAGOS.

Emi yio si da yin lohun rẹ ni kiakia ninu iwe Irohin Imọlẹ. Ti o ba fẹ kọ ibere na jọwọ kọ ki o han rekete, ki o si ri pe o ka dada nigbati o ba kọ tan ki o to fi ranṣẹ.

**For all your Printing Requirements**

Invitations, Programmes, Hand Bills, Pamphlets, Advertising Material and all Commercial Jobbing

Send your Jobs to :-
MODUPE PRINTING PRESS.
16, Bamgbose Street, Lagos. Phone: 21985

Where Quality Print, costs less.

## AWON OYINBO U. A. C. ṢE ETO ILOSIWAJU KAN NI IṢE WON TI A PE NI U. A. C PUBLIC ELATIONS DEPARTMENT.

Irohin kan jade ni owurọ ọjọ ẹti ti iṣe ọjọ Kẹtalelogun oṣu yi pe awọn oyinbo onisowo U. A. C. ṣe afikun pataki kan fun ilọsiwaju Pubic Relations Department ni Eko ati fun agbegbe rẹ. Agbọ pe wọn yan Ọgbẹni M. A. Ifaturoti si ipo igbakeji fun Ọgbẹni D. H. L. Parker ti iṣe Alakoso fun iṣẹ U. A. C. Public Relation fun Ilu Eko ati agbegbe rẹ.

Ọgbẹni Ifaforiti ti wa labẹ awọn Onisowo U.A.C fun bi ọdun kan ati oṣu mẹrin, o si ti lo diẹ ninu asiko yi lati fi ṣe iṣẹ kakiri awọn ibi iṣẹ U.A.C. ni Eko. Ki Ọgbẹni Ifaturoti to bẹrẹ iṣẹ ni ọdọ awọn onisowo U.A.C o ti ṣiṣẹ ni abẹ Ijọba Iwọ Orun Nijiria labẹ Alabojuto Ilọsiwaju Eto Ekọ. Ọgbẹni Ifaturoti jẹ ọmọ ọdun marundilogoji o si kọ ẹkọ ni ile iwe giga ti Goverment College, ni Ibadan, o si tun ṣe afikun imọ rẹ ni Ile Ẹkọ giga ti University ni Ibadan nibiti o gba oye ninu Imọ ijinlẹ (Science) ati ni University College ti Leicester ni ilu oyinbo.

## Agbegilere Omo ile Kenya



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni M. Mutisya, ti o nṣe iṣe Agbẹgilere, ọmọ ilẹ Kenya ni apa iha gabasi ilẹ Afrika on lo nṣe afihan iṣẹ awon ere ti o ti gbẹ ni inu ọdun yi fun tita ni Royal Academy nigboro London

O di ọdun karun ti Mutisya Agbẹgilere yi ti nṣe atipo nilu Oyinbo. On fi igi gbẹ ere Ọlọpa Turokana ti o nlu ilu Bẹnbẹ Oyinbo.

## KERE O! Akiyesi Pataki

**Antoin Tablets! Antoin Tablets!!**

Ẹnyin Abiyamọ lọkunrin ati lobirin. Mo ba yin yọ Eku afojuba Egbogi pataki ti aṣe iwadi rẹ lati ọwọ awọn Ọjọgbọn Oniṣegun (Specialists) Ilu Oyinbo.

Fun awọn ajakale Arun wọnyi:-

IGBONA:- Eyi jẹ Arun ti o sọpọ ni ode isisiyi papa ni arin awọn Ọmọde ati Agbalagba.

ORI FIFỌ. TULU. LUKULUKU. OTUTU. IGBAAYA ARA RIRO ati OTUTU ỌRẸRẸN pẹlu AKOKORO. Jọwọ danwo Ajẹbidan ni ogun yi. Irohin ko to Afojuba

Bere iwe ti ẹ o fi lo lọwọ ẹniti o ba ta Egbogi na fun yin. Odaju hanwuo. Ẹ o ri iṣẹ rẹ lehin iṣẹju mẹdogun ti ẹ lo. Bere lọwọ awọn Oniṣegun adugbo rẹ.

*Distributors*
HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES
26, Bishop Street Phone: 23745
LAGOS

# Petepete Tana ni Popa

Lati Ọwọ:- DELE ATỌLAGBE

KA ṢỌRA O, ỌGBẸNI ỌDẸKUNLE!

Iwọ Ọgbẹni Ọdẹkunle, mo ka ọrọ rẹ ti o jade ni ọjọ Aje ti ise 26/6/61, mo si gbọ gbogbo ọ r ọ rẹ lagboye, ninu ọrọ rẹ iwọ Ọdẹkunle nsọ pe emi Dele Atọlagbe sọ pe, mo faramọ Ipinlẹ gbigba, iwọ Ọdẹkunle tun sọpe, Aridẹgbaju ọrẹ mi ko iti sọ ero ọkan rẹ, ṣugbọn ohun ti mo fẹ ki o ye iwọ Ọdẹkunle ni wipe, ko si enikankan ti o sọ pe on ko fẹ ki Igbomina, Ọffa ati E k i t i gba Ipinlẹ, o h u n ti mo fẹ fi ye iwọ Ọdẹkunle ati gbogbo awọn ẹlẹgbẹ rẹ ni wipe, Ipinlẹ ti a fẹ gba na, kiṣe ẹgbẹ Ọlọpẹ ni yio gba fun wa, bi ko ṣe ẹgbẹ Olomi, ti o ni aṣẹ Ipinlẹ Ariwa lọwọ.

Iwọ Ọdẹkunle tun sọ pe ki awọn ẹgbẹ Olomi N. P. C- lọ jawọ kuro ninu apọn ti ko yọ, ohun ti a ko ba sọ fun ẹnyin ẹmọẹgbẹ Ọlọpẹ ni ẹnyin tun nsọ fun wa yen, Ẹnyin ti ẹgbẹ yin wọle mesan ninu i j o k o ọgọrun ati adọrin (160-9) njẹ ko ha yẹ ki ẹ fi iru ẹ g b ẹ yi silẹ? Ọdẹkunle tun tenu mọ pe, Igbomina, Ọffa ati Ekiti nfẹ Ipinlẹ kiakia, ṣugbọn Oloye G. Ademọla Ogunniyi ọmọ ilẹ wo ni ṣe? Nipa ti Ọgbẹni P. B. Olatunde to tun lọ fi ẹnu ba, o yẹ ki nsọ fun ẹ wipe bo pe titi ogun ọdun yio ku ọla ọdun marun fẹrẹ pe na, ti Ọgbẹni Ọlatunde yin yio tun wa kọju si ilẹ Igbomina wipe ki nwọn wa dibo fun on, a o ma wọ boya yio wọle tabi ko ni wọle o ti lẹ ti han gbangba wipe ẹgbẹ Ọlọpẹ ko le ri nkankan ṣe mọ ni ilẹ Igbomina, Ọffa ati Ekiti, nitoripe ninu Ibo ilẹ Ariwa to kọja yi Ọgbẹni John Ekunrin, enit' ṣe olori ẹgbẹ ti iwọ jẹ igba keji Akọwe fun, ko ri oye ba wọle bẹni Ọgbẹni Josiah Sunday Ọlawọyin papa ko ri bi ba wọle ni Ọffa, eyi si fi han pe, ni ilẹ Igbomina ati Ọffa ko si ẹgbẹ Ọlọpẹ ni bẹ mọ. Ṣugbọn mo ti sọ fun iwọ Ọdẹkunle pe, bi o ko ba ri ọrọ sọ mọ, o jẹ lọ sinmi.

Ki nto gba ọrọ iwọ Akọwe ẹgbẹ Igbomina Parapọ gbọ pe otitọ ni on sọ, jẹki nri kọpi (Copy) awọn iwe ti Ọlọla P. B. Ọlatunde kọ si Kaduna, bi o ko ba le jẹ ki nri iwe na, ẹ le nu lọ si ọdọ Olotu "Irohin Imọlẹ" ki o ba yin tẹ iwe na jade, ki a le gba pe otitọ ni Ọlatunde kọwe si Kaduna, ṣugbọn bi a ko ba ri iwe yi, a jẹ pe ogbologbo opurọ ni nyin.

Ọdẹkunle jọwọ, mo fẹ mọ iye ti on gba lo sosu fun ipo igbakeji Akọwe ẹgbẹ Igbomina Parapọ rẹ, bi o ba jẹ wipe owo ti on ri gba yi ni ko jẹ ki o le fi ẹgbẹ Igbomina parapọ silẹ, mo fẹ sọ fun ẹ pe ẹnikan ti sọ fun mi wipe, on yio ma san owo rẹ na fun ọ, iwọ Ọdẹkunle papa mọ daju pe, ẹgbẹ Ọ l ọ p ẹ ko le ri nkankan ṣe ni Ipinlẹ Ariwa mọ, jọwọ maṣe ta ilu rẹ sọnu nitori owo ti on ri gba ninu ẹgbẹ Igbomina Parapọ, mo gbọ pe ọmọ Agbele ni ọ, mo fẹ mọ ile ti o ti wa.

AWỌN IWE KO ṢE MANI
IWE EGBOGI FUN ONIRURU IWOSAN:
IWE ADURA IṢẸGUN AWỌN AJẸ:
IWE IFA AGBỌN-NIREGUN. IWE ITUMỌ ALA PẸLU IWADI NKAN:
IWE LILO ATI AGBARA PSALMU:
★ ★ ★ ★ ★ ★
IWE ADURA TETE DA MI LOHUN:



IWE ITAN ABALAIYE ATI TI IṢẸDALE
KỌWE FUN IWE-ITAJA:-
OLOTU BOX 104
EBUTE METTA, NIGERIA.

KERE O! KER E O!! ẸNYIN ARA?

# Odo ti gbe Omuwe lo o!

Lati Ọwọ: ẸNI OWỌ ỌMỌ ARIDẸGBAJU (ORO)

Ha! Ẹnyin Igbomina Ọffa, Ekiti. Wọn de o wọn tun de. Awọn Aiyeluje Oselu, awọn bi Otilẹ ri kori Oselu, awọn ti ko mọ ti ẹlomiran afi ti ara wọn nikan, wọn tun de.

Irohin kan jade ninu iwe Irohin Ojojumọ ti njẹ Daily-Times, ti ọjọ kewa Osu Kẹfa 1961. (10/6/61) Ọgbẹni J. G. Ẹkunrin ko awọn kan jọ ti wọn pe ara wọn ni Ẹgbẹ Onigbalẹ adapọmọ Igbomina Parapọ. O wa bẹrẹ si sọ ohun ti ko le mu ilẹ Igbomina, Ọffa, ati Ekiti Ọlọrun ko si ni jẹ ki Irohin Bu bu ru na ṣẹlẹ ni Ile wa Lailai, Amin. On kesi Alakoso Ijọba apapọ Naijiria pe ki o fi Oju to Ọran Ilẹ Igbomina, Ọffa, Ekiti oni awa ẹgbẹ Olomi N. P.-C. afi iya jẹ wọn pupọ, papa ju'ọ Omiran fi Ilu rẹ silẹ lọ si Ilu miran Ori Ọpọlọpọ enia ni wọn da sẹ wọn lainidi oni ẹlomiran nsan owo ori giga yatọ si awọn to ku.

Ha! Ẹnyin Ọmọ Iyami ni lẹ Igbomina, Ekiti ati Ọffa, Ẹko ro ju Aiye bayi. Nitoripe wọn ko wọle, wọn wa nsọ isokuso, Iwikuwi, Ọlọrun ko ma ni tu awa Igbomina Ọffa, Ekiti ka o. Mo bẹ Ọgbẹni Ẹkunrin ti o ba fẹ wa ọna onjẹ ninu ẹgbẹ Onigbalẹ rẹ, Ọna miran ni ki o gba wa Onjẹ. Mo wa fi ibere yi si wa ju iwọ Ọgbẹni J. G. Ẹkunrin ibere na jẹ mẹta. Akọkọ (1) daruko awọn Ilu ti o tu ka ni lẹ Igbomina Ọffa, Ekiti? Ekeji (2) darukọ awọn enia ti wọn ju sẹwọn lainidi nile Igbomina Ọffa, Ekiti? Ẹkẹta (3) daruko awọn ti wọn bu owo ori giga fun ni ilẹ Igbomina ati Ekiti? ti iwọ ko ba le dahun ibere mi yi a jẹ pe o nwa onjẹ ọjọ re ni. Ha! Ọgbẹni Ẹkunrin a dibo o nyọ ibinu, bẹni nigbati iwọ wa nile Igbimọ Kaduna iwọ ko le sọ ohun ko hun okare Adẹkẹ Mini Mini ọkẹ soge.

KOITI PARI

# EGBE IMOLE AIYE

A fi eyi ṣe ikede fun gbogbo awọn ọmọ ile ẹkọ wipe a ti da ẹgbẹ kan silẹ labẹ iwe Irohin-Imọlẹ Esin ọrọ wa ni:- Imọlẹ de okunkun parada.

Awọn ọmọ ẹgbẹ yi ni anfani lati ma sẹrọ sinu iwe Irohin-Imọlẹ, Iru ohun ti a nfẹ lọdọ wọn ni alọ, itan, owe ati irohin aladun ti o ba ṣẹlẹ loju awọn ọmọ ẹgbẹ na.

Pataki nkan ti awọn ẹgbẹ na fẹ ma ṣe ni lati ma kọ awọn ọmọde ni ẹkọ ile, hihu iwa rere, bi a ti gbọran si olukọ ati awọn obi lẹnu. Ifara bale ni 'le ati lode. Igba ara ẹni ni iyanju yio wa fun gbogbo ọmọ ẹgbẹ na.

Ohun ti o ba si ru ọmọ ẹgbẹ kan loju, ki o kọ sinu iwe, ki awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ gbọ, ki wọn ba le gba ni moran nipa ohun ti o ba yẹ fun u lati ṣe.

Orukọ ................................................

Kọ orukọ rẹ ni kikun, ki o si tobi

Ibugbe ................................................

................................................

Ile ẹkọ ................................................

Ọjọ Ori ................................................

Enikẹni ti o ba fe wọ ẹgbẹ yi ki o ge ibi ti a fi silẹ lati kọ awọn orukọ rẹ si pelu stamp tọrọ ti a o fi da esi pada si ẹ ranṣẹ si:-

Akọwe Agba,
Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye,
c/o Olotu Irohin Imọlẹ,
16, Bamgbose Street,
Lagos.

# Alaye Oro Nipa Ilu Omupo

Lati Qwo:- EGBE IGBOMINA PARAPO (A. G.) ALLINACE NANA COMPOUND OMUPO (Lagos Bra.)

Inu wa yio dun ti Olotu Irohin Imolę bale gba wa la ye lati fe si si oro Jimoh omo Alufa to jade ninu iwe Irohin Imolę ti ojo 26:6:61. Oya i lenu w pe Jimoh omo Alufa le kede iru oro bę yan sinu iwe Irohin, ki ni se ti Ogbeni J. A. Ramonu fi ito dudu sinu ti on tu funfun jade lenu, o yę ki Mallam Ramonu le so iru oro ti o ka awon omo ile Nana ni ni ojo Sunday ti se 11/6/61/ sinu we Irohin Imolę fun gbogbo ara iye ka, ti o ba ję wipe o da loju wipe oro ti o yę ki omo'uwabi enia so, lo jade lenu rę si omo ile Nana ni ojo na. Oro ti Malla Ramonu so ninu apejo omo ile Nana ni ojo na ni wipe.

Awon Egbe N. P. C. tise egbe on ti ko idamu ba opolopo awon omo egbę Olopo ni Ilu Omupo da ibiti won ko ri ile gbe, oni awon egbę on yi han na si ti wa opolopo awon omo ti nse egbę Olopę lejo ni Ilorin. La ti le ję won niya, Mallam Ramonu tun so nieu oro rę wipe ba kan na ni Egbę on N. P. C. ti se eto pari ni ilu Ilorin lati ma wa fi warrant mu awon omo Egbe Olope ti ilu Omupo to wa loiko, Mallam Ramonu ni pataki lori oro on yi ni wipe ki ile Nana tete yi ipamu won pada kuro ninu Egbę Olope ki won si wo Egbę Opolę N. P. C. ki patan iya ti Egbę on N. P.C mn bo lati Ilorin wa ba awon omo Omupo Le ko lę yę kuro lori awon ile Nana.

IYO KU DI OSE TO MBO

## Awon Egbe Odi ati Aditi ran iko lo sodo Oba Geesi



Awon meji ti a nwo ninu aworan yi ni awon ijinni enia meji ti awon Egbę ti o nwa ire ati anfani fun awon Odi ati Aditi ti o mbę nigbogbo aiye, eyiti nwon da silę nilu Amerika ran lo si'lu G e e s i lati lo fi we egbe na han Oba won Elisabeti Keji. Ohun ti o nbę ninu iwe na ni ogidinleje oruko awon enia Nlanla ti o mbę kakiri Agbaiye nwon le ni egberun ti nwon ti je ohen lati ko sinu egbę iranlowo fun awon Odi ati Aditi.

Awon meji ti a nwo ninu aworan yi, gegebi imura won fi han pe Jagun-Jagun ni awon mejeji.

IKILO FUN AWON ONIBARA WA GBOGBO NIPA RIRA AWON

## Egbogi Robirobi

Opolopo enia ni won ti sina lai ko mo nipa ilo egbogi oju didun fun inu riron, ogun sisa didun fun ogun ilera, egbogi jedijedi fun ti Lakuregbe ati orisirisi bębę, ohun ti o mu eyi wa ni pe pupo ninu awon ti won nta egbogi robirobi wonyi kakiri Igboro ko mo nipa won rara, won a si ma gbe omo oba fun osun ninu awon Egbogi papa ti won nta wonyi ko dara. Opolopo ti won npe ni "TONIKI" fun "EJE ARA" ko le se ise na rara, omi ti pojn egbogi ti won lo. Besi ni ninu awon egbogi ti won nta fun lilo awon O M O O W O ati O M O D E ko le se ise gbogbo ti won nso wipe won a ma se. Sora lati ma ra awon "Egbogi Robirobi" nitoripe "Owo" won roju ti won nta kakiri ode nisinsinyi o lewu pupo, o si nfi owo rę sofo ni pelu. Bere ojulowo egbogi orisirisi ti o ba nfe ni Sobu ti won mo dajudaju nipa "Egbogi" ti won ti wa lenu rę fun nkon bi odun medogbon sehin wa tabi ju bę lo ni Sobu awon:-

Waterloo Medicine Stores
8, PalmChurch Street, P. O. Box 333.
Lagos Nigeria. Phone: 22878

EYI NI TI EMI....

THREE THREE'S
TRIKOLA!



SWORD BRAND

TRIKOLA
333
-LXK-